Ẹni ti o ba ṣe amọ̀nà lọ sibi oore, o maa ní irú ẹsan ẹni tí ó bá ṣe e

Láti ọ̀dọ̀ Ibnu Mas’ud Al-Ansaariy- ki Ọlọhun yọnu si i- o sọ pé: Ọkùnrin kan wa ba Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o wa sọ pé: Nǹkan ọ̀gùn mi ti kú, fun mi ni nǹkan ti maa gùn, ni o wa sọ pé: “Mi o ni”, arákùnrin kan wa sọ pé: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, maa júwe fun un ẹni tí ó maa fun un ni nǹkan ti o maa gùn, ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- wa sọ pé: “Ẹni ti o ba ṣe amọ̀nà lọ sibi oore, o maa ní irú ẹsan ẹni tí ó bá ṣe e”.

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Ọkùnrin kan wa sọdọ Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pé: Ràkúnmí mi ti parun, ba mi wa ràkúnmí kan ti maa gun ti o maa gbe mi de ibi ti mo n lọ, Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- mu àwáwí wa fun un pe oun ko nii nǹkan ti o le gun, arákùnrin kan ti o wa nibẹ wa sọ pé: Irẹ ojiṣẹ Ọlọhun, maa júwe ẹni tí ó máa fun un ni nǹkan ọ̀gùn fun un, ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- wa sọ pé alabaakẹgbẹ nibi ẹsan ni fun ẹni ti o ba fun un ni nnkan ọ̀gùn; tori pe oun ni o júwe rẹ fun ẹni tí ó ni bukaata si i.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/5354